MO RI ENMỌ L'EREKO AJA WỌ EWU O RO'SỌ

## Ikede

Awọn ikede yi fun gbogbo ọ̀rẹ́ Oluwe wa ati aṣoju wa wipe, ẹni kẹni ti owo ba sẹku si owo rẹ ki o tete fi ranṣẹ nitori gbogbo ohun elo ti a fi ntẹ iwe irohin lo ti gbe owo leri.

Ẹnikẹni ti ko ba fi tire ranṣẹ ao da iwe rẹ duro ao si sa agbara lati gba owo wa ni owo rẹ. Olotu


ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

FEDERAL ELECTION

AUGUST 11, 1955

Vote For Adewale

(The boy is good)

VOL. VII No 426 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA JULY 30 1955, IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI. (2d)


## Okun Bata To Ja Ọrọ Di Ikale



QBA ALAFIN QYQ

ILESHA— Qro rogbodiyan ti Qba Alafin di oro pese nisisiyi, a gbo wipe awon egbe alakuko (N.C.N.C-) ti lo fi adeke de ayonusi ti nwon, oro na wa di ti awon to ni eto lati so si.

Awon to ni eto lati so si oro oba Alafin ni awon Alase Ijoba Iwo-Orun, ki lo kan awon egbe Alakuko ninu oro yi? ko ye wa to!

Awon Yoruba l'o ma ns wipe "kini a ti nin itan aja ki o to kan Lemomu" oro ile Yoruba se di ti ko-gbede?

E je k'a sinmi.

## Agbako Ori Ede

Lati owo ESUBELEKE

Adura ti gbogbo enia ngba l'aiye lojojumo ni pe ki Olorun maje ki a pade agbako. Eyi fihan ni pe Anjonu buburu ni agbako, ko si eloraye to raye ju agbako lo; iru ni, ki ng won lobe.

Agbako a ma yo si enia lojiji nigbamiran; nigba pupo ewe, elomiran nfi iwa ati ise re polowo bi eni npolowo oja kakiri ilu pe "Eniti o ba ni agbako ki o ta fun on."

ATAGO KO EYIN APARO

Ohun ti oju wa, l'oju eri. Ole, Omutipara, Pansaga, Agbere, Abinueni, Ofofo, ati iwa awon oni jaduku - iwa miran bi awon Awamoto niwakuwa, aibikita fun emi omo enia, ni gbogbo won gbe opa wahala dani funrawon, ti nwon si nwa agbako kiri lojojumo.

Bi iru awon enibe ba pade agbako nibiti agbako lugo si bi ode, ohun ti oju wa, ni oju ri. Sibesibe, gbogbo enia ni yio ma k'anu won. A ko so wipe gbogbo eniti agbako mba l'o fi owo arare nfa, sugbon "Okete ni bi oro ba de ibi iru k'afo" niti awon Awamoto ni iwa aibikita fun emi awon enia to nfi ese rin wa onje ojo won kiri.

ORO AGBAKO KI IBA MO

A se akiyesi pupo ninu awon awa-Moto ti nwon je omoluwabi, paapaa awon to ni Moto ti nwon nwa fuurawon, sugbon ti awon omojeka, oku ko mo iye ti a da ago ni ti won, digbolu, kolu ni nwon fi nwa Moto onimoto kiri; l'asiko kan nilu wa yi, awon awa-Moto ti nwon npe ni "Bo'le k'aja" lona Agege, nigbati okan won le tan, Bakaya, eran Oniyo ni nwon npe awon enia to fi ese nrin l'ona ti Olorun ba yo oluware ti Moto won ba re koja.

A dupe pupo lowo awon alase Ijoba wa, awon olugbimo iselu wa (Lagos Town Council) ti nwon se die ninu awon opopo ona ilu wa ni ona kan fun Moto, ti jamba agbako Moto fi dinku larin ilu Eko. A si tun be won, ki nwon ba wa se eto be si awon ona to ku ti awon ona

(Wo oju ewe kefa)

# Mo Ri Enmo L'Ereko Aja Wo Ewu. O Ro'So

Eko Ni ojo Satide ti ise ojo ketalelogun osu yi ni ohun iyanu kan sele ni oja Ereko, ti o je akoya l'ona fun t'omode-t'agba awon enia.

Ohun iyanu na ni wipe odomodebinrin kan sode, eleyinju-ege kan ti o gbe omo re pon si ehin, ni omo ti o gbe pon na sesi bo lule lati ehin re, kini a tun ma ri lehin eyi, nse ni omobinrin arewa yi bo gbogbo aso ara re sile, ni o wa bo si ihoriho gedegbe, l'oba bere si sare lo wonu oja ati yika oja, gbogbo enia ti o ba ko l'ona, o di igbe l'a nfewe, oko l'a nwa nkan obe, akoya bara ni nwon nfi ise.

Nitoripe ko si eniti o le ri ti ko ni sebi nwon sese gbe orisa fun sin ni. (Iyen ni wipe o sese wo were) eyi je ohun iyanu fun opolopo enia, sugbon nigbati a se iwadi irufe asa bee, awon alagba enia fi ye wa wipe, ETUTU ni nwon nfi iwa na se. bi omo ba bo lehin iya re, iya ti omo bo lehin re lule nilati se gegebi odomodebinrin na ti se. Eyi je asa ile Yoruba.

Nje mo ri enmo l'Ereko, aja wo ewu, o ro'so.

## Owo Te Ole Aji Eran Gbe

Eko Irohin ko to afojuba ni osan ojo Alamisi ni dede agogo mokanla koja bi iseju medogun nigbati ariwo nta gee, wipe ole! Ole!! Aji eranagbo gbe, Ole!!!

Ero to egbagbeje lori okunrin giripa kan ti o lo ji eran agbo tu l'ori iso ni oja Ajegunle ti nwon npe-ni (Jankara).

Nigbati owo te jagun ole osangangan yi, nse ni o mbebe, Qro ti de odo awon Qlopa,

Kil'o sun e debe,

Eyi je, eyi ko je!

## ATUNSE

L'oju ewe karun iwe wa yi, a si oruko ogbeni Isau Qlanrewaju Adewale ko bi Liasu Qlanrewaju Adewale. E s'akiyesi re o.

# ELETI QFE

A-NIJU-WQN KO SE WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS — CABLES & TELEGRAMS

28 Kosoko Street, Lagos — "ETI-QFE LAGOS"

P. O. Box 467 — Phone 23370

VOL. VII NO. 426 LAGOS SATURDAY JULY 30 1955

## Qba Adele, Dakun o.

Ninu ose keji ti o lo ni a se isiti kekere kan jade ninu iwe Irohin wa oloyinmomo nipase ti ede-aiyede ti o fe be sile l'arin awon omo-oye nile Onisemo.

Ninu ikede wa ti a so yi, a ko fi epo bo iyo rara lati wi ti asaran fun asar an kio ye aran se, sugbon bi a ba fi owo bo oju; agbon isale ni ao pari re si, idi re ni a fi fe tun mu enu kan oro oye na ni ekan si.

Awon Yoruba monimoni ni o ma npa owe bayi wipe "Ako ni so wipe oju Malu tobi titi ki a ma le ti obe bo," toto o, a juba enyin agbagba. Bi o ti wu ki oro kan tobi to, enu ni a ma fi so.

A fi ikede wa ose yi be Qba wa Kabiyesi Adele II wipe ki o fiyedenu, dakun se suru, bi o ba tile fi owo wo'nu, ti o si fa awon apa kini, apa keji, ati apa keta mora, kiakia ni ede-aiyede ti o fe ba nkan je yi yio yanju.

KI QBA KI O PE

## Oru Pa Enia D'orun

**Warri** Awon obinrin meta pelu omo-owo kan ni oru pa Ku d'orun nilu yi.

A gbo wipe nwon da ina Edu sile nitori otutu to nmu lasiko yi nwon si ti ilekun iyara ti nwon sun si, nigbati ile ojo keji mo, ti awon aladugbo ko gburo won, ni won ba lo si ilekun iyara won, oku gbogbo awon meteta pelu omo-owo ni nwon ba.

Imoran: Olotu Enyin enia wa o ye ki e fi eyi kogbon, ki olukuluku mo wipe ina edu ki ise nkan ti enia le da sinu iyara ti yio si ti ilekun iyara na mo. Ise jamba ti oru ina *edu* nse niyi.

## Eku Qdun Eku Iyedun

## Oluwa Ko Fi Qpo Qdun Han Wa O

## Ale Gbe Iyawo Salo

Lojo ose ti o koja, Ogbeni Jimo omo Idofiyan da iyawo duro, gbogbo awon ara ile re si njo, nwon yo, laimo wipe ko de okan iyawo. Ni ojo keio awon kan ti nwon ti nba iyawo soro tele wa ba se adehun ati gbe sa lo.

Loto nigbati o di agogo mejo ale, iyawo duro ni enu ona ita ile, awon agbewiri ti gbe taxi de gegebi adehun ti nwon jo se nwon sare gbe iyawo sinu taxi, nwon si fi ina s'oko.

Lojo ti nkan yi sele oko iyawo ko si nile, awon ara ile si ndaro lasan ni.

## Ana'wo Eru Farakorin

AMERIKA.... Qkunrin ara ilu Swizerland ka l'olo se jam a lodo obinrin ota'ja kan, o ra oja oni Ponun marun, o si fi Iwe owo eru kan s'arin owo daradara merin fi san owo fun obinrin na.

Obinrin to ja fafa yato, l'ogan obinrin na ti yo Iwe owo eru jade larin owo atata, ki a to seju pe, awon Qtelemuye ti ra qkunrin na mu

K'ama fa oro gun, Adajo fi s'ewon odun merinla pelu ise asekara. E lo sora pelu owo eru nina o,

## Alhadji Abdul Raheem Noibi

ALASO - OKE MOSQUE.

Ope ni fun Oluwa nipa ase to pa fun wa ti o si ni ki a mu ase na se ni eyiti o je odun Ileya, ohun ni o je odun ti o tobi niwaju Oluwa, a si dupe fun gbogbo awon elesin ti o gbe Olorun ga l'okunrin l'obinrin, Oluwa ko so emi gbogbo wa di opolopo odun lati ma se agbega fun Oluwa. Awon ti o ti se, Oluwa ko dariji nwon, ki o gba irun ati eran ti nwon pa, ati awon ti ngbe Mecca ati nihin ki Olorun gba ise wa.

Assalam Alaikum.

## Chief Eletu Odibo Prime Minister To Qba Adele Of Lagos



CHIEF ELETU EDIBO

Mo ki gbogbo ijoye, o bere lori Adeniji Adele II Qba Eko, Kabiyesi, titi lo fi kan awon Musulumi ni gbogbo ile karo ojire. E ku odun e ku Iyedun- A seyi Samodun.

## E Ku Ewu Qdun O

Ogbeni S. A. Majerahun (Alias QFE) ki gbogbo awon Onibara re, awon gbajumo to ngba aga lodo re ku odun Ileya, ku Iyedun, ki Qlorun fi opo odun han wa o.

## Qjo Kan Ko Dun Bi Qjo Keji Ileya

A fi wosika wayi ki gbogbo enyin Qkawe wa, enyin Asoju Iwe Irohin wa Eleti-Qfe ati enyin ore wa nile, l'oko, l'odo ku ewu odun, e si ku Iyedun, ki Oluwa se odun na ni odun rere fun wa, odun owo, odun-omo odun alafia baba iwa.

OLOTU

## Tani Le La Idi Oro Yi Yemi?

OLOTU

Mo pade oro mi kan ti mbo lati Oko Ode, o ko Aparo merin lowo. Mo si ni ore i, bun mi lokan ninu re, o ni rara, on yio je okan si enu ara on, on yio fi okan san gbese, on yio ta okan lawin, on yio so okan nu.

Mo si ni eyi ti o ma sonu yen, kio kuku fun mi niyen. O ni han koye e ni, o so wipe ki nwon lo bi awon agbalagba bi mererin ti je.

Ki awon okawe jowo l a eyi yemi.

Emi ni
Alufa Amuda Iwalewa

## Idahun Si Ibere deyeye

OLOTU

Gba mi laye lati dahun si ibere Ogbeni M. O. Adeyeye ara Abidjan ti o nfe mo nipa awon Afin, emi gan li o si ye lati dahun si ibere na.

Orisa kan mbe ti a npe ni Obatala. Aye ko gba to lati so iru ise ti Orisa yi nse. Sugbon gbogbo awon Alabuku ara, gegebi Atiro, Aro, Asuke, Afin, Odi, Aditi, Afoju, Akepa, ati awon bawonni li a npe li "Eni-Orisa" idi re ti a se npe won be ni pe nigbati nwon se Obatala, ni Orisa se sewon be.

Ko si eda enia ti ko mbi omo Afin. Gbogbo eyi ti irun ori re ba funfun laiti di arugbo ninu Oyinbo je Afin.

Bi enia ba nse ahun pupo, ojo ti o ba se si orisa yio bi Afin lomo sugbon Afin ko gbodo bi Afin li omo. Kodi ki iya je Afin, ki baba si je afin awon ko gbodo bi Afin, nitori orisa akunle bo ni Afin paapa je.

Afin pe oris meta. (1) Afin gidi ti gbogbo ara re dabi ti oyinbo. (2) Ko je oyinbo ko si je enia dudu, ti ara re fin kala-kini (3) eyi ti gbogbo ara re dudu ti oju re dabi ti Ologbo. sibe-sibe, Afin ni gbogbo won. Ahun li o mu enia bi Afin.

Emi ni
Imam Adeen

## Adelabu Se Afojudi Si Kotu

**Ibadan, Irohin ti a gbo ni wipe Ogbeni Adegoke Adelabu, ti o wo'le nigbati nwon dibo ni Ibadan lose to koja ni wipe nwon ti fun ni iwe Ip'ejo fun afojudi to lo se pelu awon omo ehin si Kotu Oja'ba ni'lu Ibadan.**



**A si gbo wipe Ogbeni Ade Bal'o ti Ise isongbe Alaga Igbimo Ibile na ti gba iwe Ipejo tire bakanna. Awon mejeji yio farahan niwaju Adajo ni ojo Monday ojo kedogbon osu yi.**

## Ilosiwaju Fun Ilu Ilorin

Lati Owo Akowe Egbe Afenifere

OLOTU,

Inu mi yio dun pupo ti e bale gbami ni aye die ninu iwe irohin yin lati le ba gbogbo awon omo ibile ilu Ilorin ati agbegbe re soro die lori eto ilu wa nipati Ijoba orile ede wa ni iha Ariwa.

Gegebi omo ibile Ilorin, o je ohun iyalenu wipe gegebi gbogbo ilu miran se nni ilosiwaju, ilu Ilorin, koni ilosiwaju rara gegebi okan ninu awon ilu ti o tobi ti o si wa ni ile Ariwa.

Niwonba igbati o je wipe o ju tubo nlasi dada yi, ti olukuluku si nwa ominira, ko ye ki o je wipe iru ilu Ilorin ni o tun fa sehin rara.

Awon egbe ti won je ijoba fun ile wa, ko se anfani kankan si ilu wa rara kaka be, atan. ni anri wipe nse ni won tan wa je.

Oye ki ani awon nkan wonyi INA LENTIRIKI (STREET-LIGHT), RADIO ati ki gbogbo ONA Titi (Roads) igboro wa ni ODA kari patapata gegebi gbogbo awon ilu miran ti ri.

Lehin eyi, afe ki ijoba ma ya awon agbe ati Onisowo ni owo (Loan) gbogbo eyiti moka sile yi ni nwon ti se ileri re fun wa ki ato dibo fun won wole ninu idibo ti o koja lo yi laiko mo pe iro ni won fi gbogbo inkan wonyi pa fun wa nigbana.

Nisisiyi, gbogbo omo ilu Ilorin ti ri pe iro ni egbe olomi (N.P.C.) npa fun wa ni Ilorin nibi ati wipe titori ki ale dibo fun won ni won se npa iro yi fun wa. Sugbon gegebi owe Yoruba ti o so bayi pe "Ina Esisi ki njo ni lemeji," a ti gba pe ko tun si iru iro, ti omo egbe olomi (N.P.C.) tun le pa fun wa ni Ilorin mo ti a le gba nitoripe awa kotun ni dibo fun omi mo rara.

Nitorina, "atan ni do ko le tani do lemeji," enikeni ti o ba je omo ilu Ilorin toto, ti o si nfe ilosiwaju ati anfani fun ilu Ilorin, ki o dibo fun Ope ti egbe Afenifere (Action Group.) Enikeni ti o ba nwa ire fun ori ara re, ilu re, ati orile ede re ki o dibo fun egbe Afenifere (Action Group) nitoripe egbe yi nikan ni o le mu ilosiwaju ba ilu ati orile ede gbogbo.

Fun idi pataki yi, afe ki gbogbo omo ibile ilu ilorin ati agbegbe re, ki o lo wo egbe Afenifere ki o si pada kuro lehin egbe olomi (N.P.C.) Nitoripe, lati nkan bi odun merin sehin ti egbe Olomi ti nse Ijoba ile wa bo, ako iti ri ise rere won konkon ti won se si arin ilu wa rara, ase ileri mamuse ni egbe Olomi je, won koto lati gbekele rara, nitoripe won korira otito, ire ati ilosiwaju gbogbo nkan. Nitori idi eyi, Edibo fun Egbe Afenifere (Action Group) fun Idera gbogbo anfani gbogbo, ati idunnu gbogbo.

Lati owo akowe
Egbe Afenifere, Ilorin.

## Madam Modinatu Alaga Ebute-Ero

Mo ki gbogbo Imam Oba Imale, E ku ipalemo odun. ti a ba seyi tan a o tun se miran si, O tan wa bere lodo Kabiyesi ti o fi kan gbogbo ijoye. Olorun jeki a se opolopo odun, ati awon ara ilu Alamadiya Ansaru-deen, Alalukurani, ati Alasalatu, gbogbo nwon ni mo ki, ati gbogbo oloja, o bere lati ebute ero, Iya Eko. Mo ki o ati otun ati osi, e ku ewu odun.

## Ishola Salawu Olori Alawo Agege

Mo ki gbogbo agbaiye fun ti odun Ileya yi. Olorun jeki emi se opolopo re Olorun ko se alye ni irorun fun wa Araose oluwa Olorun ko gbe wa wa Olorun ko se wa l'ale mi gigun laiye. Kase opolopo odun Assalam Alaikum


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamo ewa ra **Omorela** dara pupo fun awon omode

A ma je ki omode ri orun nso dandan, o dara fun omuto ike ati orisirisi arun miran ti o ma nbe omode je ni asiko eyin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode.

# Omorela Baby Mixture

SILE MEJI ABO (2/6d) FUN IGO KAN
O wa lodo:

# Commercial Medicine Stores

QUALIFIED CHEMIST
10, Victoria Street Lagos

## Chairs For Rent

APPLY
OFE
NO. 3, ALIBU STREET LAGOS

## Adewale Fi Agbo Sebe, Oyinmomo

Orin ni o nsiwaju ote, awon ara Eko ni o ma nkorin bayi nigba ojo wonni, fun ogbeni Ologbe Sanni Adewale, Abiru bamba, afija po'molekun po'molerin, ninu odun ileya, orin na lo bayi:-

Adewale pa agbo sebe, oyinmomo, ara Eko gba ketowo, oyinmomo'. Bi ogun ba lo, ogun abo, orin kanna yi ni a tun nko fun omo bibi inu re loni, on ni Qgbeni Liasu Adio Qlarenwaju Adewale. The Boy Is Good.

E. O. Fakayode ati Ganiyu Agbaje. Agb'ejoro Ijoba ogbeni B. A. Adedipe ni o wa fun Ijoba.

## Won Da Alufa Sile L'ewon

VIENA— Nipa iwe ebe ti Olori Alufa (Bishop) ti ilu Hungary ko si Alakoso (Premier) Ijoba ilu Hungary wipe ki nwon o dakun, jowo wo ojo ori alufa Mindszenty, ki nwon o da s le.

Alufa Mindszenty yi ni eniti nwon ti fi si ewon lati osu February 1949 lati lo ojo ori re l'ogba ewon, fun esun odale, Ofofo ati oja okunkun.

Ijoba gba, nwon si da alufa na sile n'tori ojo ori re di odun metalelogota atipe ko tile ni alafia ara to mo.

## Muhamed Ati Jesu Je Qmo Baba

Olotu,

Mo fe lati fi han gbogbo enia wipe Muhamad ati Jesu je omo Abraham ati wipe ko si iyato ninu ede won. Qmo meji ni Abraham bi, Isiaka ati Ismaila.

Jesu j de lati inu iran Isiaka, Muhamed si jade lati inu iran Ismaila.

Lati fi kan wipe ede kanna ni nwon nso, Iwure ni Larubawa npe ni Al-Duayi Heberu npe ni Al-Dora.

Jesu so bayi wipe Talitakumi ni ede Heberu sugbon ede Larubawa so bayi pe Ta-hal anta umi, itumo kanna ni nwon ni. Jesu tun so bayi wipe Eloi, Eloi, Lama-Sabakta-ni, ni ede Heberu, sugbon Larubawa so bayi wipe, Aloha, Aloha lama sabakta na. Itumo kanna ni nwon je. Iba iyato ti o mbe larin Igbagbo ati Imale ni wipe, awon Igbagbo so wipe nwon pa Jesu sugbon Imale so pe Jesu koja eniti enia le lupa.

Emi ni
Lemomu Ajakuta


## Irora Ibadi

Egbogi ti a so fun oyi.

Nigbati ibaradi ba ndun ni, oluwa re nfo itoju bi a ko ba tete fi egbogi re ko loju alaan yi a ma fe Ehin-didun, Lakure-rbo, Wodi-wodi, Ako Esanri ati Igunfe-b iruku wa.



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba ise tara, sugbon b enia ba ti lo egbogi yi alafia yio desi oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti dise. Danwo lo ra ni gbogbo egbogi.

DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles


## Okunrin Kan Sa Iyawo Re L'ogbe.

**Aba** Okunrin kan ti oruko re nje Ekpendu nilu Aba, ni a gbo wipe o sa iyawo re l'ogbe, nigbati owo olopa te, ti nwon mu de iwaju adajo, ejo ti odaran yi ro ni wipe on ko ni ife ati pa obinrin on gegebi esun ti nwon fi on sun yi.

O so fun adajo wipe Iyawo on Love Ekpendu ti on sa logbe yi lofa ibinu na, nigbati o nro ejo kiri wipe on ko arun ran-on. O tun so wipe iru ejo buruku ti iyawo on nro mo on yi je ohun itiju fun on, ni on ba se fi oke kekere (Matchet) se ise si lara. On ko ni ero pipa si iyawo on na.

Adajo ni on gba pe o jebi, ki o lo si ewon osu mesan pelu ise asekara, nitoripe iwa to bu le panla.

## Talo Mo Ehin Qla

Qkunrin Alawo kan ti o ma nfi awon ko eja li Ebute Ehingbeti, ti bere si de awon fun eja lati owuro titi osan fi pon ti ko pa eyo akan kan de ipo ti yio pa eja.

Awon ti o mba okunrin na fa Awo wa bere si k'are. Sugbon Baba Alawo yi nda won li ekun wipe ki nwon mu suru, ki nwon si fi oriti, nitori a ko mo ohun ti Qlorun yio se kia to lo sile.

Baba alawo na fi Omiro se Aluwala nisoju gbogbo enia, o pase fun awon omose re pe ki nwon si ma lo simi, nitori awo fifa won ku igba kansoso o bo si apa kan o yan Nafila mefa, o si pe awon omo re pe o ya, bi a ba de nigba kan yi, a ri pa, tabi a ko ri pa ile ni ao ma lo.

Nigbati nwon de awo lote yi, agbara awon enia mefa na ko le fa awo na, nwon ni lati ke si awon ti o duro loke fun iranlowo.

Wo mi na, Awo! nigbati nwon fa awo yi goke ogedegede eja Qbokun ni nwon pa Eja ti nwon si ta loju na je Poun mesan ati si'le mokanla. Bi o ba se lekan ti ko bosi fun gbidanwo, nigbana iforiti re yio yori si rere, iwo yio si segun, Sa ma gbidanwo nigba gbogbo.

## Penkelemesi Ni Kotu Onireke

**Ibadan** Ejo ti won pe Qgbeni Adegoke Adelabu wipe o se afojudi si Kotu, nigbati oro na de iwaju Adajo ni Kotu Onireke l'ojo Monday ose yi, ogbeni Adelabu wipe on ko jebi esun na.

Bakanna ni Qgbeni Lasisi Ade Bello ti nwon fi sun esun meji pe o lu won o dapa si won lara wipe on ko jebi.

Adajo ye ejo won si ojo Ajme ose yi. Loya ti awon odaran mejeji gba ni Qgbeni


## Always Read And Advertise In Eleti Qfe

Mo Gbadun Siga PIRATE




PIRATE
NI SIGA TO DARA JU

# Awon Akeko Itoju Aisan Ewe.



Aworan ti a nwo ni iwe wa yi n'ti awon omobinrin wa ti nwon nko Ise itoju alaisan nilu Oyinbo Gesi.

Eniti o wa niwaju ni omidan Gemma Belgrave ti ilu Trinidad. Omidan Henrietta Jones ti ilu Eko l'owa lehin. Awon mejeji l'o nkose lati gba iwe iyege fun ise itoju awon omode kekeke to ba nsaisan.

Ise kiko fun odun meta-meta ni awon omidan omobinrin mejeji yio ko ni Ile Iwosan ti a npe ni "Ile Iwosan ti Oba Obinrin," (Queen Mary's Hospital.) Ile Iwosan ti o tobi julo fun itoju awon omo - ere ni gbaiye,

Omidan Belgrave ti de Ile Iwosan na lati odun 1953, o si ti yege ninu apa kinni ati apa keji idanwo to se ninu osu October 1954, ise tire pelu ti omo ikose elegbe re kan l'o dogba fun oye kekere ti itoju aaisan ti ile Iwosan na.

No. 98.

## Commission Of Enquiry Into Adequacy Of Government Pensions.

It is announced for general information that representations from interested bodies and individuals for consideration by the above Committee should be addressed to the Chairman of the Committee (the Accountant-General of the Federation, c/o Treasury, Lagos) and the envelope should be marked "Pensions Committee".




(O Bere loju ewe kini)

## Agbako Ori Ede

be ko ni aye to fun Moto meli lati koja arawon laisi jberu

Lowo agbako ejo, Moto, Besikulo ti akowaba-adawnba, oro oloro, Oluwa rere gba wa o.

## Egbe Alakuko Luku-Deti

Lati Owo Ayiluka

Igbe esin ndi enia, o ti pe ti egbe Alakuko ti nyaju, ti nwon mbe ibekube ni ilu Eko, sugbon ni ti ode oni, Egbe Alakuko ti nroko de ibiti orisa ma gba oko won.

Haba, kini de se! Won da enia lerinmeji. o ni on tun fe gberi, ija wa di ija ole, bi o ba la ole mole, a ma kigbe wa lu mi pa ni, Ogbeni Bensini ti Subu ni emeji ninu oro ibo.

Oloye Awolowo gbe sanle ni Ibadan, Ogbeni Akiyemi gbe subu ni Eko, o wa tun somo Adewale ni ese wipe wa lu mi pa ni.

Orin kekere yi ni ao ko fun Ogbeni Bensini:-

"O nfi iku sere o,
o nfi iku sere,
Bensini, l'onfi iku sere"

## Egbe Afenifere E Ku Alejo

**Jos** A fi eyi dupe lowo Olola Alhaji S.O. Gbadamosi to wa si ilu Jos, wa be awa omo Egbe Afenifere wo (Action Group).

Ninu pade ti a se lojo Jimo, Alhaji ba wa soro iwuri pupo ina re si dun nigbati o ri bi awon omo egbe ti po to ni ojo na, awon omo egbe to 300 enia, awon to si tun wo egbe lojo na je 100 enia 50 ni awon Hausa to wo egbe lojo na.

Awon omo egbe se ibere adota oro lowo Alhaji wa, o si fun won l'esi gbogbo re yekeyeke, eyi mu ki inu awon omo egbe dun gidigidi. Lati ojo na ni ipade wa ti nkun to si nlo deedee. Eniti o se adura lojo na ni Alhaji Mustafa Jatto, ki ipade to tuka.

A be awon alase Ijoba Iwo-Orun ki nwon ma gbinyanju lati wa ma be awa omo-Egbe wo nilu Jos awon enibi:- Oloye wa Olola Obafemi Awolowo ati Oloye Rotimi Williams.

## E Ku Odun O

Mo ki gbogbo Imale ni gbogbo ile karo e jire, ku odun, e ku iyedun, olorun ko se odun na l'abo' kase opo odun laiye.

Assalam alaikum
Alufa Yusufu Amuda.
31, Binuyo St, Lagos.




Printed & Published ... 78 Forsyth Street : P. O. Box 467 Lagos Phone 23370